# Ṣé ki n fun yin ni iro nipa eyi ti o daa julọ ninu awọn iṣẹ yín, ati eyi ti o mọ julọ ninu rẹ lọdọ Oluwa yin, ati eyi ti o ga julọ ninu rẹ ninu awọn ipo yin

Lati ọdọ Abu Dardaa- ki Ọlọhun yọnu si i- o sọ pe: Anabi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- sọ pé: "Ṣé ki n fun yin ni iro nipa eyi ti o daa julọ ninu awọn iṣẹ yín, ati eyi ti o mọ julọ ninu rẹ lọdọ Oluwa yin, ati eyi ti o ga julọ ninu rẹ ninu awọn ipo yin ti o si loore julọ fun yin ju nina wura ati fadaka lọ, ti o si loore julọ fun yin ju ki ẹ pade ọta yin ki ẹ si ge awọn ọrun wọn ki wọn si ge ọrun yin lọ? Wọn sọ pé: Bẹẹni. O sọ pe: "Iranti Ọlọhun- ti ọla Rẹ ga-".

[O ni alaafia] [Tirmiziy ati Ibnu Maajah ati Ahmad ni wọ́n gba a wa]

Anabi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- beere lọwọ awọn saabe rẹ pé: . Njẹ ẹ fẹ ki n fun yin ni iro ki n si kọ yin ni eyi ti o daa julọ ninu awọn iṣẹ yin ati eyi ti o niyi julọ ninu rẹ ati eyi ti o ga julọ ninu rẹ ati eyi ti o mọ julọ ninu rẹ lọdọ Ọlọhun Ọba Olukapa- Alagbara ti O gbọnngbọn- ? . Ti o ga julọ ninu rẹ ninu awọn ipò yin ninu alujanna? Ti o loore julọ fun yin ju ṣíṣe saara pẹlu wura ati fadaka lọ? Ati eyi ti o daa julọ fun yin ju ki ẹ pade ọta yin fun ogun lọ, ki ẹ si ge awọn ọrun wọn ki wọn si ge ọrun yin lọ? Awọn saabe sọ pe: Bẹẹni a fẹ ìyẹn. Anabi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- sọ pé: Iranti Ọlọhun- ti ọla Rẹ ga- ni gbogbo asiko ati lori gbogbo isẹsi.



النجاة الخيرية
ALNAJAT CHARITY
لجنة الدعوة الإلكترونية
EDC E-Da'wah Committee